# Ète Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú Àṣàyàn Orin Fújì Saheed Òṣùpá

*Adéye□mí Abío□□dún Adéyínká Ph.D.*


## Àṣamọ̀

*Fújì jẹ́ ọ̀kan lára ẹ̀ka orin eré ijó Yorùbá tí ó dìdelẹ̀ láti ara wéré/ajíwéré, tíí ṣe orin ẹ̀sìn músùlùmí fún àsìkò ààwẹ̀. Àwọn onímọ̀ ìṣáájú ti gbájúmọ́ àwọn ẹ̀ka orin Yorùbá mìíràn bí i wákà, àpàlà, jùjú nígbà tí iṣẹ́ díẹ̀ tó wà lórí orin fújì pàápàá jùlọ orin Saheed Oṣupa gbájúmọ́ ṣíṣe àyẹ́wò Saheed Òṣùpá gẹ́gẹ́ bí òṣèré apètepèrò ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ. Èrèdí iṣẹ́ tiwa yìí ni láti ṣe àfihàn àwọn ète tí gbajúgbajà òǹkọrin Fújì nì, Saheed Òṣùpá, lò láti fi dá àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lẹ́kọ̀ọ́ nínú àwọn orin fújì rẹ̀ àti láti fi mọ̀ bóyá àwọn ète rẹ̀ tí ó lò náà jẹ mọ́ ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà dá àwọn ọmọ wọn lẹ́kọ̀ọ́. Bákan náà, láti ṣàfihan pé gbogbo ọ̀nà tó fi dórí orin ni àwọn Yorùbá máà ń ṣàmúlò rẹ̀ láti fi ẹ̀kọ́ kọ́ àwọn ọmọ wọn. Tíọ́rì ìfojú-ìmọ̀-ìbára-ẹni-gbé-pọ̀-láwùjọ wò/sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀ ni a gùnlé láti mú kí iṣẹ́ ìwádìí yìí kẹ́sẹ járí, nítorí pé pàtàkì orín láwùjọ Yorùbá tayọ ìdárayá lásán. Bẹ́ẹ̀ gẹ́lẹ́ ni àwọn orin Saheed Òṣùpá kún fún ọ̀pọ̀ àti ète ìdánilẹ́kọ̀ọ́ láwùjọ. Ọgbọ́n ìwádìí lílọ détà àtẹ̀ẹ́lé àtọwọ́dọ́wọ́ (secondary data) ni olùwádìí lò láti wádìí abẹ́nà ìmọ̀ rẹ̀; Saheed Òṣùpá. Ọlùwádìí lo èyí nítorí pé gbogbo akitiyan rẹ̀ láti rí Saheed Òṣùpá lójúkorojú ló já sí pàbó. Àwọn àṣàyàn àwo orin Saheed Òṣùpá tí ó lò ni Ẹni ìṣòro bá kọ ni mọ ri, Àṣẹ́rú lè dọmọ, Barrybrattion, Ọ̀làjú dé àti Bó o bá yó ko pánú. Nípasẹ̀ lílo ọgbọ́n ìṣètúpalẹ̀ aṣàlàyé kókó-ọ̀rọ̀ (thematic analysis), ìtàn nínú orin; ìlù; ìyánrọ̀fẹ́rẹ́ láti inú ìrírí pẹ̀lú ìyá rẹ̀; àṣàyàn ọ̀rọ̀ àti ìyánrọ̀fẹ́rẹ́ láti inú Kùránì súyọ gẹ́gẹ́ bí ète ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú àwọn orin Saheed Òṣùpá. Bákan náà, ní ìbámu pẹ̀lú tíọ́rì sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀, àwọn ète ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú orin Saheed Osupa wà ní ìbámu pẹ̀lú ọ̀nà tí àwọn Yorùbá ń gbà dá ọmọ lẹ́kọ̀ọ́ láwùjọ. Ní ìbámu pẹ̀lú àwọn èsì ìwádìí, olùwádìí gbà àwọn ọ̀dọ́ ní ìmọ̀ràn pé kí wọ́n máa gbọ́ orin Saheed Òṣùpá pẹ̀lú ọkàn láti rí ẹ̀kọ́ dì mú nínú àwọn orin náà, kí wọn má ṣe máa gbàgbé ara wọn sínú ìlù àti àlùjó inú orin nìkan bí kò ṣe láti máa fọkàn bá a lọ nínú àwọn ẹ̀kọ́ tó ń kọ́ nínú rẹ̀.*


*Kókó ọ̀rọ̀:* *ète, ìdánilẹ́kọ̀ọ́, àṣàyàn orin, fújì*

## Ìfáárà

Àwùjọ Yorùbá jẹ́ èyí tó mú ẹ̀kọ́ kíkọ́ lọ́kùn-únkúndùn. Ìdí èyí ni wọ́n sì ṣe máa ń pa òwe pé "ọmọ tí a kò kọ́ ní gbé ilé tí a kọ́ tà." Èyí fi pàtàkì ẹ̀kọ́ hàn láàárín àwọn Yorùbá. Ìdí rẹ̀ sì nìyìí tí ojúṣe kíkọ́ ọmọ lẹ́kọ̀ọ́ kì í ṣe ojúṣe òbí nìkan tó fi jẹ́ pé bí òbí bá bímọ sílẹ̀ tán, àti fún irú ọmọ bẹ́ẹ̀ lẹ́kọ̀ọ́ tó bá àwùjọ wọn mú tí di ojúṣe gbogbo ènìyàn láwùjọ. Abájọ tí àwọn Yorùbá ṣe máa ń sọ pé 'ojú mẹ́rin ní í bímọ, ìgbà ojú ní í wò ó." Èyí fi hàn gbangba pé àwùjọ Yorùbá kò fi àyè gba ìgbé aye kóńkójabele kálukú ló ń ṣe tirẹ̀ torí pé "àgbájọọwọ la fi ń sọ̀yà" lọ̀rọ̀ wọn. Gbog-

bo ọ̀nà pátá ni wọ́n máa ń sán láti kọ́ àwọn ọmọ wọn ní ẹ̀kọ́, èyí ló sì fà á tó fi jẹ́ pé gbogbo ọ̀nà, gbogbo ìgbà àti ibi gbogbo ni wọ́n máa ń ṣàmúlo láti rí i dájú pé àwọn ọ̀dọ́ wọn mọ ọwọ́ ọ̀tún yàtọ̀ sí òsì, ìdí rẹ̀ nìyìí tó fi jẹ́ pé ìwà ọmọlúwàbí fẹsẹ̀ múlẹ̀ dáadáa tí ayé sì tòrò pẹ̀lú nítorí pé gbogbo ayé ló ń tẹ̀lé ètò àti àlàkalẹ̀ àwùjọ. Nípasẹ̀ ẹ̀kọ́ kíkọ́ yìí ni àwùjọ fi máa ń mú kí àṣà àti ìṣe wọn tẹ̀síwájú láti ìran kan sí ìkejì, wọn kì í sì fi ojú rere wo ẹnikẹ́ni tí kò bá ní ẹ̀kọ́ náà, àwọn bíi ẹ̀kọ́ ìwà, ìbọ̀wọ̀fágbà, ìtẹpámọ́ṣẹ́, ẹ̀kọ́ bí a ṣe ń sọ̀rọ̀, bí a ṣe ń múra abbl.

Lóòótọ́ ni pé ẹ̀kọ́ yìí kì í ṣe tí kíkọ àti kíkà, ṣùgbọ́n àwọn ọ̀nà kan wà tí àwùjọ máa ń gbà tọ́ àwọn ògo wẹẹrẹ wọn sọ́nà, ṣebí ẹyin lo ń di àkùkọ, ọmọdé òní ni yóò sì di àgbàlagbà ní ọ̀la. Bí àwọn wọ̀nyìí bá ṣì ṣe rí ni yóò sọ bí ọjọ́ọ̀la àwùjọ náà yóò ṣe rí. Ẹ̀kọ́ náà máa ń wáyé ní gbogbo ọ̀nà nípasẹ̀ àwọn bí òwe atọ́nisọ́nà, ìtàn lóríṣìíríṣìí, àlọ́ àpamọ̀, àlọ́ àpagbè, orin lóríṣìíríṣìí, ọ̀rọ̀ àgbà abbl. Gbogbo àwọn wọ̀nyìí ni wọ́n máa ń fi kún ọgbọ́n, ìmọ̀ àti òye ẹni tó bá gba irúfẹ́ ẹ̀kọ́ bẹ́ẹ̀.

Ní ilẹ̀ Yorùbá, orin jẹ́ ọ̀kan pàtàkì lára àwọn ọ̀nà ìdánilẹ́kọ̀ọ́. Orin tí ó mú ọgbọ́n dání pẹ̀lú ọ̀rọ̀ ìjìnlẹ̀ wọ́pọ̀ láàárín àwọn Yorùbá. Wọ́n máa ń dá ọgbọ́n láti kó gbogbo àwọn èròjà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ bí òwe, àkànlò èdè, àṣàyàn ọ̀rọ̀, ìtàn akọ́nilọ́gbọ́n abbl. sínú orin wọn. Wọ́n á sì gbé e kalẹ̀ lọ́nà tí yóò wu etí gbọ́.

Adélékè (2012) ṣàlàyé pé orísìíírísìí ni àwọn ẹ̀yà orin tí a ní láàárín àwọn Yorùbá. Bí a bá fi ojú ìlànà èrò ìlù tí a lù sí àwọn orin pín wọn sí ìsọ̀rí, àwọn ẹ̀yà orin tí a máa ní nìyìí: àpàlà, fújì, sákárà, wákà, wéré, dadakúàdà àpíìrì, àyúù àti àwọn orin ijó mìíràn. Púpọ̀ iṣẹ́ ni àwọn onímọ̀ ti ṣe lórí àwọn orin Yorùbá wọ̀nyí, pàápàá jùlọ lórí ọ̀rọ̀ òṣèlú nínú orin àpàlà àti fújì (Fádípẹ̀, 2016; Egbokare àti Fádípẹ̀ 2016); ìdáàbòbò ìtàn ìṣẹ̀dálẹ̀ nínú orin jùjú (Olúdáre, 2018); àṣà Yorùbá nínú orin ìbílẹ̀ (Yussuf àti Olúbòmẹhìn, 2018); àfiwé ipa ẹ̀sìn mùsùlùmí nínú orin àpàlà, wákà àti sákárà (Olúsọjí, 2008); àgbéyẹ̀wò Saheed Ọ̀ṣùpá gẹ́gẹ́ bí òṣèré apètepèrò ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ (Bámgbóṣé, 2016) àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Bí àwọn iṣẹ́ wọ̀nyí ṣe dára tó, wọ́n kò tíì fi bẹ́ẹ̀ gbájúmọ́ ṣíṣe ìtúpalẹ̀ ète ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú orin fújì pàápàá jùlọ orin Fújì ti Saheed Ọ̀ṣùpá, tí a yàn fún iṣẹ́ tiwa yìí.

Bákan náà, àwọn ọ̀dọ́ òde-òní kò fi gbogbo ara fẹ́ràn orin Fújì nítorí pé ọ̀pọ̀ nínú wọn gbà pé orin àwọn púrúǹtù ni, àwọn mìíràn kò fẹ́ràn rẹ̀ nitori pe kì í ṣe ohun tí ó wù wọ́n láti gbọ́ ni àwọn òǹkọrin fújì máa ń kọ nínú àwọn orin wọn; kìkìdá àwọn ọ̀rọ̀ aṣa, àwọn àṣà ilẹ̀ òkèèrè ni wọ́n fẹ́ láti máa gbọ́ léyìí tí kò ní ṣe wọ́n ní ànfààní kankan, èyí sì mú wọn máa káràmásìkí àwọn orin tàka-súfèé ju orin fújì lọ. Ohùn tó wá wúni lórí jọjọ nínú orin fújì Saheed Ọ̀ṣùpá ni pé, òun gan fúnra rẹ máa ń fira rẹ̀ sí ipò ọ̀dọ́ tí ó sì mọ ohun tí wọ́n fẹ́, gẹ́gẹ́ bí i òǹkọrin tó ní ọgbọ́n, ó máa ń lo àwọn ọ̀nà tí yóò mú kí irúfẹ́ àwọn ọ̀dọ́ yìí ni ìfẹ́ láti gbọ́ orin fújì rẹ̀ tí wọn yóò sì rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ ọgbọ́n àti ẹ̀kọ́ fà yọ nínú rẹ̀, àwọn ète wọ̀nyìí ni iṣẹ́ ìwádìí yìí yóò yẹ̀wò fínnífínní. Gẹ́gẹ́ bí a ti sọ síwájú, a ó rí i pé òǹkọrin bíi olùkọ́ ni olórín yìí.

Ṣùgbọ́n ṣá púpọ̀ ọ̀dọ́ ni kò nífẹ̀ẹ́ sí orin fújì. Púpọ̀ nínú àwọn tó nífẹ̀ẹ́ sí i náà

kò kọbí ara sí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ inú àwọn orin fújì. Lọ́pọ̀ ìgbà, àlùjó àti àríyá inú orin náà ni wọ́n máa ń fi ọkàn bá lọ tí wọ́n sì máa ń gbàgbé wí pé ó ní iṣẹ́ pàtàkì tí òǹkọrin náà ń fi orin rẹ̀ jẹ́ fún àwùjọ yàtọ̀ fún ìdánilárayá nìkan. Èyí jẹ́ ẹ̀dùn ọkàn fún wa gẹ́gẹ́ bíi olùwádìí nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ẹ̀kọ́ ló máa ń jẹ jáde nínú àwọn orin fújì, pàápàá jùlọ àwọn orin Saheed Ọ̀ṣùpá tí a yàn fún iṣẹ́ yìí.

## Ìgbéǹde àti Ìdàgbàsókè Orin Fújì

Orin fújì jẹ́ ìfarahàn ìdàgbàsókè àti àyípadà orin ẹ̀sìn Islam sí orin àkànṣe tó gbajúgbajà (fújì) nílẹ̀ Nàìjíríà. Orin fújì tún jẹ́ ìdàgbàsókè àti àkójọpọ̀ gbogbo àwọn ìpèdè inú àwọn orin bíi sákárà, wákà, àpàlà. Níwọ̀n ìgbà tí ó ti jẹ́ pé wéré ni ó para dà di fújì, dandan ni kí á sọ̀rọ̀ lẹ́kùnún-rẹ́rẹ́ lórí wéré. Gẹ́gẹ́ bí Ọmọ́jọlá (2014) ṣe sọ, kí ó tó di ìgbà ọdún ìtúnu àwẹ̀ (Id-il-fitri) tó máa ń wáyé lẹ́yìn àwẹ̀ Ramadan, lásìkò àwẹ̀ àwọn ọ̀dọ́ ìlú máa ń péjọ láti kọrin láàrin ara wọn. Ní ìdájí kùtùkùtù hài àwọn ọ̀dọ́ máa ń kọ orin wéré káàkiri àdúgbò láti jí àwọn Mùsùlùmí fún sààrì àti àdúrà láti bẹ̀rẹ̀ àwẹ̀ ọjọ́ náà èyí ni wọ́n pè ní jíjí wéré. Ibi wéré yìí ni orin fújì tí ṣẹ̀ wáyé. Nípasẹ̀ ṣíṣe èyí, àwọn Mùsùlùmí tó lówó lọ́wọ́ máa ń nawọ́ ọrẹ sí àwọn ọ̀dọ́ yìí, èyí náà sì jẹ́ ìwúrí fún wọn láti múra sí jíjí wéré náà kódà nínú àwọn tó jẹ́ àǹfààní èyí ni gbajúgbajà olóṣèlú nì M. K. O. Abíọ́lá (Ọláolúwa 2011).

Nípasẹ̀ ìgbéǹde láti ìpìlẹ̀ ẹ̀sìn yìí fújì ti bẹ̀rẹ̀ sí ní àwọn ìràwọ̀ òṣeré láti nǹkan bí ọdún (1960). A rí àrídájú pé ní ọdún 1965, wọ́n gbé ìdíje ife-ẹ̀yẹ Nnamdi Azikiwe kalẹ̀, èyí wáyé ní gbàgede Evans (Evans Square, Èbúté Mẹ́ta, ìlú Èkó) fún àwọn ọ̀jìnnì ajíwéré níbi tí Kọ́láwọlé Ràsákì Àyìnlá, tí a mọ̀ sí Kollington (kébé-n-Kwara) àti àwọn ẹgbẹ́ ajíwéré rẹ̀ borí ìdíje náà. Èyí fi òpin sí gbogbo awuyewuye tó sì fìdí rẹ̀ múlẹ̀ pé àwọn ẹgbẹ́ olórin ajíwéré ti wà kí ó tó di ọdún 1980. Láti ọdún 1980, orin fújì ti la ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìdàgbàsókè àti ìyípadà kọjá láti ìpele ìṣẹ̀dá lọ sí ìpele ìdàgbàsókè àti ìyípadà tó fi dórí ìpele àyípadà lóríṣìíríṣìí. Ìpele ìṣẹ̀dá ni ìgbà tí àwọn ajíwéré máa ń kó ara wọn jọ láti máa jí àwọn èèkàn Mùsùlùmí láti jí jẹun tí wọn yóò sì tún máa dá wọn lára yá pẹ̀lú. Àwọn ohun èlò orin tí wọ́n máa ń lò nígbà náà ni àfọ́kù ìgò, òfìfo agolo, igi, gángan, sákárà pẹ̀lú àwọn ìlù ìbílẹ̀ mìíràn, tí èdè orin wọn máa sábà jẹ́ èdè Lárúbáwá pẹ̀lú àwọn ọ̀rọ̀ inú Kùránì (Ọmọ́jọlá 2014).

Ìpele ìdàgbàsókè ni àsìkò tí orin fújì gbèrú sí i kúrò ní ipò ìṣẹ̀dá lọ sí ìpele tó rí ẹsẹ̀ walẹ̀ tó sì ga ju ti àtẹ̀yìn wá lọ, ìkòríta yìí ni wọ́n ti gbé àwọn àwọn ohun èlò orin ìbílẹ̀ patì tí wọ́n sì fi àwọn ti ìgbàlódé bíi kóńgà, bóńgò, clappers, maracas, àti tambourine rọ́pò, tí àwọn òṣeré fújì sì bẹ̀rẹ̀ sí ṣeré ni àwọn ilé ìtura, gbàgede ńlá tó fi mọ́ àwọn ilé-iṣẹ́ ìgbóhùnsáfẹ́fẹ́. Èyí tó kẹ́yìn ni ìpele àyípadà lóríṣìíríṣìí, níbẹ̀ ni orin fújì ti ṣe àmúwọlé àwọn ohun èlò orin tó yanrantí ju ti ìṣáájú lọ, àwọn bí ohun èlò orin alátẹ̀dún (electric keyboard), fèrè ìgbàlódé (trumpet), saxophone àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ sí inú orin fújì (Adéṣọ̀kàn 2004).

Orin Fújì jẹ́ ọ̀kan pàtàkì nínú ìpínsísọ̀rí orin Yorùbá. Àrànkáyé ni oòrùn ràn ni orin fújì jẹ́ nítorí pé káàkiri ilẹ̀ Yorùbá ni ó ti jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà. Èyí kò jọ ní lójú púpọ̀ nítorí pé nínú ìsọ̀rí orin Yorùbá, orin fújì nìkan ló ń bá ìgbà yìí, à ṣé òtítọ́ ni òwe Yorùbá tó sọ pé bí ayé bá ń yí ká máa bá a yí, bí ìgbà bá ń yí ká máa bá ìgbà yìí torí ẹni tí kò bá bá ìgbà yí ẹni náà yóò bá ìgbà lọ ni. Lótìítọ́ ni pé àwọn ènìyàn ń gbọ́ orin fújì ṣùgbọ́n oníkálukú ní àwọn olórin fújì ààyò nínú àwọn olórin fújì wọ̀nyìí nítorí pé ohun tó wù mí kò wù ọ́ ni kò jẹ́ kí ọmọ ìyá méjì pawọ́pọ̀ fẹ́ obìnrin kan ṣoṣo.

Kò yani lẹ́nu pé ìṣọwọ́ kọrin àti ìjẹlógún àwọn olórin fújì yàtọ̀ sí ara wọn, níbi tí èdè ti jẹ ẹlòmíràn lógún ni ẹ̀kọ́ ti jẹ ẹlòmíràn lógún, kódà ọ̀rọ̀ òṣèlú jẹ ẹlòmíràn lógún púpọ̀ nínú wọn, òmíràn a fi gìrìgìrì kọrin nigbati ó jẹ́ pé jẹ̀lẹ́ńkẹ́ ni ti ẹlòmíràn, èyí ló sì fà á tí àwọn olùgbọ́ wọn náà fi máa ń yàtọ̀ sí ara wọn bó tilẹ̀ jẹ́ pé a rí nínú àwọn olùgbọ́ orin fújì tó fẹ́ràn ju olórin kan ṣoṣo lọ. Nínú gbogbo àwọn olórin fújì lóríṣiríṣi yìí, Saheed Òṣùpá ni a yàn láàyò nínú iṣẹ́ yìí. Ìdí nìyí tí a ó fi kọ́kọ́ sọ̀rọ̀ nípa ìtàn ìgbésíayé rẹ̀ àti orin rẹ̀ kí á tó kán lu agbami ìtúpalẹ̀ tí iṣẹ́ yìí dá lé.

## Ìgbésíayé Saheed Òṣùpá àti Orin Rẹ̀

Ọmọ Ìbàdàn ní Ayẹ́yẹ́ ni Saheed Òṣùpá. Ó lọ sí St. Mary Roman Catholic Missionary School ní Ajégúnlẹ̀ fún ilé-ẹ̀kọ́ alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ̀, Schools Village, Mile 2, ní ìlú Èkó, àti ilé-ẹ̀kọ́ gbogbo-nìṣe The Polytechnic Ibadan. Lẹ́yìn èyí ni ó lọ sí ìlú òyìnbó láti lọ kọ́ ẹ̀kọ́ nípa computer engineering pẹ̀lú Networking níbi tí ó ti gba ìwé ẹ̀rí Diploma. Kò pẹ́ kò pẹ́ yìí ni ó lọ sí ilé-ẹ̀kọ́ Fásitì Ìbàdàn níbi tí ó ti ń kọ́ ẹ̀kọ́ ìmọ̀ nípa òṣèlú lábẹ́ ẹ̀ka ẹ̀kọ́ ọlọ́nà jínjìn (DLC).

Ilé ni Saheed Òṣùpá ti bá orin nítorí pé bàbá rẹ̀ náà Olorin Etíyẹrí, Wéré abbl ni. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé èyí kò ní ṣe pẹ̀lú yíyàn tí Saheed Òṣùpá yan iṣẹ́ orin kíkọ láàyò nítorí pé bàbá rẹ̀ kò fi gbogbo ara fọwọ́ sí orin kíkọ rẹ̀, sùgbọ́n bí a bá fi ojú mìíràn wò ó, a ó rí i pé àjẹ́bi ni orin kíkọ jẹ́ fún Saheed Òṣùpá. Saheed Òṣùpá bẹ̀rẹ̀ sí ní kọrin láti nǹkan ọmọ ọdún mẹ́wàá sí méjìlá, bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ó yà sí ìdí eré orí ìtàgé fún ìgbà díẹ̀ kí ó tó wá padà yan orin fújì kíkọ ní ààyò. Nígbà tí Saheed Òṣùpá bẹ̀rẹ̀ sí ní kọrin, kò ní elégbè kankan, òun nìkan ló máa ń kọrin tí yóò sì máa gbè é fúnra rẹ̀. Ó jẹ́ ká mọ̀ pé òun máa ń kópa nínú ìdíje wéré tí ó máa ń wáyé nínú agboolé wọn níbi tí gbogbo àwọn akópa pẹ̀lú òun gan-an ti gbọ́dọ̀ ṣẹ̀dá orin tuntun tí ẹnìkan kan kò tíì kọ rí, níbẹ̀ ni ìwà kí á máa ṣẹ̀dá orin tuntun ti mọ́ ọn lára.

Eré ọ̀fẹ́ ni Saheed Òṣùpá fi bẹ̀rẹ̀ níbi tí yóò ti máa lọ sí òde eré láì gba kọ́bọ̀ ní ọdún 1983 sí 1984 kí ó tó di ẹni tí ó rí ṣe nídìí iṣẹ́ orin tí ó sì di gbajúgbajà. Ó ti kọ ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin tí àwo orin rẹ̀ sì ti fẹ́rẹ̀ẹ́ tó ogójì. Ó ṣe àpatẹnu jẹ́wọ́ pé òun ní àwọn "composers" tí wọn máa ń ràn òun lọ́wọ́ lẹ́ẹ̀kọ̀kan láti bá a ṣẹ̀dá orin tuntun ṣùgbọ́n kì í ṣe gbogbo ìgbà torí òun gan-an náà a máa ṣẹ̀dá ọ̀pọ̀lọpọ̀ orin fúnra rẹ̀. Ó

fi kún-un pé òun ṣe rẹ́kọ̀dù àkọ́kọ́ òun “Fuji Fadisco” ní ọdún 1993 bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé ọ̀fẹ́ ni òun gbé e fún àwọn alágbàtà.

Lára àwọn àwo orin náà ni a ti rí ‘Fújì Boogie’, ‘Fújì Fadisco’, ‘Fújì Blues’, ‘Demonstration’, ‘Stainless’, ‘Master Blaster’, ‘London Delight’, ‘Endorsement’, ‘Turn by turn’, ‘Capability ‘, àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ. Ní àfikún, ó jẹ́ kí ó di mímọ̀ fún wa pé Saheed Ọ̀ṣùpá ti kọrin káàkiri ní orílẹ̀-èdè Nàìjíríà àti ní àwọn ilẹ̀ òkèèrè bí Amẹ́ríkà, London, Canada àti ilẹ̀-Adúláwọ̀ lórísìírísìí. Ó ní ìyàwó, ó sì bí ọmọ pẹ̀lú, bí Ọlọ́run ṣe fún un ní ọkùnrin náà ló fún un ní ọmọbìnrin.

Orin márùn-ún nínú àwọn orin Saheed Ọ̀ṣùpá ni a yàn fún iṣẹ́ yìí. Àwọn orin tí a yàn náà nìyí:

1. Ẹni ìṣòro bá kọ ni mọ ri
2. Àṣẹ́rú lè dọmọ
3. Barrybrattion
4. Ọ̀làjú dé
5. Bó bá yó ko pánú

Àwọn kókó tí ó sáábà máa ń jẹ jáde nínú àwọn orin rẹ̀ ni bí ìṣẹ̀lẹ̀ àwùjọ, ọrọ ìgbéyàwó, ìjà àgbà ìgbéga àṣà. Saheed Ọ̀ṣùpá máa ń sábà lo àwọn kókó-ọ̀rọ̀ náà gẹ́gẹ́ bí kókó ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ni. Ó sì ní àwọn ète tí ó máa ń gùn lé láti mú kí ìdánilẹ́kọ̀ọ́ náà kẹ́sẹ járí. Àwọn ète wọ̀nyí ni ó jẹ wá lógún nínú iṣẹ́ ìwádìí yìí.

## Ète Ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú Orin Fújì Saheed Ọ̀ṣùpá

Àwọn ète tí ògbóǹtarìgì akọrin fújì nnì; Saheed Ọ̀ṣùpá ń lò láti fi dá àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lẹ́kọ̀ọ́ nínú àwọn orin rẹ̀ tí a yàn fún iṣẹ́ yìí ni:

**Ìtàn nínú orin**: Nínú àṣàyàn orin tí a gbé yẹ̀ wò (ìgbà ìpọ́ ńjú là ń mọ ọ̀rẹ́), Saheed Ọ̀ṣùpá fi orin náà sọ ìtàn nípa àwọn ọ̀rẹ́ méjì kan tí wọ́n yan iṣẹ́ apẹja láàyò gẹ́gẹ́ bí iṣẹ́ òòjọ́ wọn. Ọ̀rẹ́ àkọ́kọ́ máa ń rí ẹja pa déédéé tí ìkejì kì í sì rí ẹja pa, ṣùgbọ́n eléyìí tí ó ń rí ẹja pa náà máa ń fún èyí tí kì í rí ẹja pa ní ẹja jẹ yálà ó tóbi àbí kò tóbi. Kẹ̀rẹ̀kẹ̀rẹ̀, èyí tí kì í rí ẹja pa tẹ́lẹ̀ bẹ̀rẹ̀ sí ní rí ẹja pa, ṣùgbọ́n kàkà kó rántí ọ̀rẹ́ rẹ̀ tó ń ràn án lọ́wọ́ tẹ́lẹ̀ ní ṣe ni yóò lọ pe àwọn tí kò rí i nígbà tí kò rí ẹja jẹ tẹ́lẹ̀ tí àwọn ọ̀rẹ́ arírebánijẹ yìí yóò wá máa yọ ọrẹ rẹ̀ tó máa ń fún un ní ẹja jẹ tẹ́lẹ̀. Ẹ̀kọ́ tí ó fà yọ nínú ìtàn yìí ni pé ọwọ́ epo ni ayé máa ń bá ni lá, wọn kì í bá ni lá tẹ̀jẹ̀ àti pé ìwà oníwà ni àwọn ènìyàn máa ń wù bí owó kò bá tí í dé ọwọ́ wọn, ó di ìgbà tí ọwọ́ wọn bá ba ohun tí wọ́n ń wá tán kí ìwà wọn gangan tó fojú hàn

**Ìlù:** Saheed Ọ̀ṣùpá lo ìlù láti ṣe ìdánilẹ́kọ̀ọ́ fún àwọn olùgbọ́ rẹ̀, ìlú gángan ni àwọn onílù rẹ̀ máa ń lò láti ṣe èyí. Ìlù gangan yàtọ̀ díẹ̀ nínú àwọn ìlú Yorùbá nítorí àbùdá ọ̀tọ̀ tí ó ní, ìlù gángan tí wọ́n máa ń fi awọ ewúrẹ́ ṣe ni àwọn onílù máa ń lò láti fi sọ̀rọ̀, ohun tó ń jáde níbẹ̀ ni a lè túmọ̀ sí ohùn tó bá wù wá, Yorùbá

ló pòwe pé kò kúkú sẹ́ni tó mọ èdè àyàn bí ẹni tó mú kọ̀ǹgọ́ ẹ̀ dání, ẹni tó lomele ló mọ ohun tí ń fomele sọ. Nítorí èyí, bí onílù bá ti fi ìlù sọ̀rọ̀ ni ẹnìkan nínú ẹgbẹ́ wọn yóò túmọ̀ rẹ̀ fún aráyé kí àwọn abanilórinjẹ́ má ba à bá wọn túmọ̀ rẹ̀ sí nǹkan mìíràn nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ìtumọ̀ ní a lè fún ohùn ìlù. Nínú àṣàyàn orin rẹ̀ (à ṣẹ́rú lè dọmọ), ó sọ ìtàn ráńpẹ́ kan níbi tí àwọn ẹ̀dá ìtàn rẹ̀ ti jẹ́ àyàn. Gbàgede ìlú ni ibùdó ìtàn náà lásìkò ọdún ìbílẹ̀ wọn, wọ́n pe onílù wọn tí wọ́n fẹ́ràn láti fi ìlù dá wọn lára yá, ó bẹ̀rẹ̀ sí ní lu ìlù, ṣùgbọ́n nígbà tí ó yá ó lù ìlù kan tó bí àwọn ènìyàn nínú, wọ́n kìlọ̀ fún un títí ṣùgbọ́n kò gbọ́, èyí ló sì fa ìkórìíra fún un lọ́dọ̀ àwọn ènìyàn tó nífẹ̀ẹ́ rẹ̀ tẹ́lẹ̀ tí wọ́n sì pé onílù mìíràn, onílù yìí ló wá lu ìlù fún wọn pẹ̀lú ìrẹ̀lẹ̀, ó lù báyìí pé;

*Dán dàn dán dàn dán dán dán, dán dàn dan*

*Dán dàn dan dàn, dán dàn dán dàn dán*

*dàn dan dàn, Dàn dàn dan dàn*

*Ìtumọ̀:*

*Títẹ̀ là á tẹ̀lú sẹ́ka, ó tẹ̀lú / Béyàn kan mọ̀, tó rò póun mọ̀ tán / Ìwọ̀n to mọ̀, nìkàn lo mọ̀*

Lóòótọ́, àwọn ará ìlú kọ́kọ́ ń kùn pé onílù náà kò lọ́lá ṣùgbọ́n lọ́gan tí ó gbọ́ ni ó ṣe àtúnṣe tí gbogbo àwọn ará ìlú sì padà fẹ́ràn rẹ̀ dáadáa.

Ẹ̀kọ́ tí a rí fàyọ níbi yìí ni pé ìgbéraga ló ń ṣíwájú ìparun, ẹ̀fọ́ kì í yin ara rẹ̀ lọ́bẹ̀, tótó ó ṣe bí òwe àwọn àgbà, ìgbéraga a máa mú kí ohun tí ènìyàn ń ṣe níyì lójú aráyé di arípòṣé, ayé á ní 'orí rẹ̀ wú ju iṣẹ́ apá rẹ̀ lọ' èyí yóò sì mú ìfàsẹ́yìn bá ẹni náà dípò ìgbéga àti ìtẹ̀síwájú látàrí ìmọ̀ tí ó ní àti ìmọ̀ọ́ṣe rẹ̀, èyí ló fà á tí àwọn ìlú fi kórìíra ọkùnrin àyàn onígbèéraga náà tí àtẹ ìlẹ̀kẹ̀ rẹ̀ sì di àtẹ ọ̀rúnlá, èyí tún wà ní ìbámu pẹ̀lú ẹsẹ Bíbélì tó sọ pé ' ẹni tó bá rẹ ara rẹ̀ sílẹ̀ ni a ó gbé ga'. Ohun kóhun tí a bá ń ṣe, kí a má torí pé ó bọ́ sójú ọwọ́, ká yé máa rò pé kò sí irú wa nítorí pé irú Ọlọ́run ni kò sí, irú ènìyàn pọ bí i ewé rúmọ.

Saheed fi hàn pé kò sí ẹni tí ó pé tán, bó ṣe wù kí ènìyàn mọ̀ ọ́n ṣe tó, ó ní láti kù síbìkan. Ní ìgbàkúùgbà tí wọ́n bá pe wá sí àkíyèsí ìwà kan, nìṣe ni ó yẹ kí á ṣe àtúnṣe kíakíá, kò sẹ́ni tó kọjá àṣìṣe, fún ìdí èyí, kò yẹ kí inú ènìyàn bàjẹ́ tí wọ́n bá pè é sí àkíyèsí ìwà kan tí kò dára tàbí àìṣedéédé kan.

**Ìrírí pẹ̀lú ìyá rẹ̀:** Yorùbá máa ń sọ pé bí ọmọdé bá láṣọ bí àgbà, kò lè ní àkísà bí àgbà àti pé ohun tí àgbà bá rí lórí ìjókòó bí ọmọdé bá gorí igi àjà kò lè rí i. Ìdí rẹ̀ nìyìí tí wọ́n ṣe máa ń sọ pé ìrírí ló mójú àgbà jìn (ìrírí làgbà). Ìdí rẹ̀ nìyìí tí Saheed Ọ̀ṣùpá ṣe máa ń lo àwọn ìmọ̀ràn tí ìyá rẹ̀ máa ń fún un wọ inú orin rẹ̀ láti jẹ́ kí ó lè máa tọ́ àwọn ènìyàn sọ́na kí wọ́n má ba à ṣi ẹsẹ̀ gbé.

**Lílé***: Bó bá yó ko pánú*

*Ko má rankùn bọnbọ*

*Torí páyé gbẹgẹ*

*Ègbè :Bó bá yó ko pánú*
*Ko má rankùn bọnbọ*
*Torí páyé gbẹgẹ*
**Lílé***: Àwọn tẹ jọ jẹ́ sàwáwù*
*Kí wọn tó tẹ̀ síwájú*
*Ó ti wá tẹ̀ síwájú*
*O ti jù Wọ́n lọ one time*
*Bó bá dùn máwọn kan ńnú*
*Kò lè dùn máwọn kan ńnú*
*Torí bílé ayé yìí ṣe rí ni*

Saheed Òṣùpá gbé orin yìí lé orí òwe Yorùbá tó sọ pé bí iṣu ẹni bá jinná, a máa ń dawọ́ bò ó jẹ ni torí a kò mọ ẹni tí inú rẹ̀ kò dùn sí ohun tí à ń ṣe, gbogbo aláàmù ló kúkú da ikùn de lẹ̀, a kò mọ èyí tí inú ń run, tótó ṣe bí òwe àwọn àgbà. Nílé ayé yìí, kò sí ẹnì kankan tí ó fẹ́ kí ẹlòmíràn ju òun lọ, àyàfi òbí ẹni nìkan, kódà kì í ṣe gbogbo òbí gan án.

Gẹ́gẹ́ bí ó ti sọ nínú orin náà, ó bẹ̀rẹ̀ pẹ̀lú àwọn tí ènìyàn jọ jẹ́ ẹgbẹ́ yálà nípa ọjọ́ orí tàbí ipò kan náà, tí wọ́n bá jọ ń ṣọ̀rẹ́ tí wọn ń fẹyín sí ara wọn, wọn a dọ́gbọ́n máa wo ẹṣin ara wọn sáré kí ọ̀rẹ́ wọn má baà yọrí jù wọ́n lọ, ní ààrín irú àwọn ọ̀rẹ́ wọ̀nyìí, bí ọ̀kan bá ní àgbéga lẹ́nu iṣẹ́ lááárín wọn, inú wọn kò ní dùn sí i, inúnibíni, ìlara, ìkùnsínú yóò bẹ̀rẹ̀ lááárín wọn, púpọ̀ nínú wọn a sọ ọ́ di ìjà, àwọn mìíràn lè dẹ páńpẹ́ sílẹ̀ fún un láti kó sí nítorí pé gbogbo ọ̀nà ni wọn yóò máa sán láti sọ ọ́ di èrò ẹ̀yin padà, ṣe èèrà ò kúkú fẹ́ ti pòpórò dénú pé ará ilé ẹni kò fẹ́ ká kú bẹ́ẹ̀ ni wọn ò fẹ́ ká rùn ṣùgbọ́n wọn kò fẹ́ ká jẹ́ ènìyàn bọ̀rọ̀bọ̀rọ̀. Torí èyí ni Saheed Òṣùpá fi gba àwọn ènìyàn àwùjọ ní ìmọ̀ràn pé 'Bó bá yó ko pánú ko má rankùn bọnbọ torí páyé gbẹgẹ.

Yàtọ̀ fún àwọn tí ènìyàn jọ jẹ́ irọ̀, ìlara tún máa ń ṣẹlẹ̀ láàrin ọ̀gá sí ọmọọ̀ṣẹ́, bí ọmọọ̀ṣẹ́ kan bá di ọ̀gá, tàbí gba ìgbéga lẹ́nu iṣẹ́, bí irú rẹ̀ bá yọ láyọ̀jù, àwọn ọ̀gá rẹ̀ tẹ́lẹ̀ yóò máa wò ó pé àwọn ti jọ di ẹgbẹ́ àti pé irúfẹ́ ìtẹríba tó ń fún àwọn tẹ́lẹ̀ lè dínkù, inú irú àwọn ọ̀gá yìí kò ní dùn sí i tí wọn yóò sì máa wá gbogbo ọ̀nà láti gbé e ṣubú. A fẹ́ ká jẹ, má fẹ́ ká yó tí ń fún ní lóko ìdí ọ̀pẹ ro lọmọ aráyé àfi kí Ọlọ́run máa kóni yọ.

**Àṣàyàn Ọ̀rọ̀:** Èyí ni àwọn ọ̀rọ̀ tí kò wọ́pọ̀ nínú ìsọ̀rọ̀ ojoojúmọ́ ṣùgbọ́n tí a máa ń sọ láti yànnànà ọ̀rọ̀, ó dà bí lílo àkàwé ọ̀rọ̀ kan àti ayọrísí rẹ̀ láti yànnànà ìṣẹ̀lẹ̀ kan tó ń lọ lọ́wọ́ àti àyọrísí rẹ̀. Saheed Òṣùpá kúndùn láti máa lo èyí nínú orin rẹ̀ lọ́pọ̀lọpọ̀.

Nínú orin rẹ̀ tí a gbé yẹ̀ wò fún èyí, oríṣìíríṣìí àṣàyàn ọ̀rọ̀ ni ó fi dá àwọn olùgbọ́ rẹ̀ lẹ́kọ̀ọ́, ó sọ̀rọ̀ lórí ìwà, ọ̀lẹ àti ìkà pẹ̀lú ìgbẹ̀yìn wọn

**Lílé***: Ayé ẹ dákun ẹ gbà gbà gbà gbà gbà*
*Ẹ gbàyí ẹ gbéyìí wo*
**Ègbè***: Ẹ dákun ẹ gbà gbà gbà gbà gbà*
*Ẹ gbàyìí ẹ fi kọ́gbọ́n*
**Lílé***: Ayé fárí igún o, wọn tàkàlà lẹsẹ̀*
*Ká ronú ká tó hùwà ná fi dá tàtíòro sí*
*Àgbẹ̀dẹ ń rọkọ́o, àgbẹ̀dẹ ń rọ bàbà*
*Ẹ gbọ́ ná ta ni ó rọ̀wà sẹ́ni tí ò níwà ńnú*
*Ẹ dákun ẹ gbà gbà gbà gbà gbà*
*Ẹ gbàyí ẹ gbéyìí wo*
**Ègbè***: Ẹ dákun ẹ gbà gbà gbà gbà gbà*
*Ẹ gbàyìí ẹ fi kọ́gbọ́n*

Ohun tí Saheed Ọ̀ṣùpá ń fi hànníbí ni pàtàkì ìwà rere, ó fi àwọn ẹyẹ mẹta ṣe àpẹẹrẹ; igún, àkàlà àti àtíòro. Ó ṣàlàyé pé ìwà pẹ̀lẹ́ àtíòro ló jẹ́ kí aráyé dá irun orí rẹ̀ sí tí kò jẹ́ kí wọ́n fá a bí i ti ẹyẹ igún. Ó sì fìdí rẹ̀ gúnlẹ̀ pé **ìwà lẹwà ọmọ ènìyàn.**

Ó tún sọ nípa ìkà náà:

**Lílé***: Béèyàn kan bá yídó borí o, tó tún tafà sókè*
*Ẹ sọ fúnkà kó má yàyọ̀jù, kó retí ẹ̀san rẹ̀ á ké*
*Ká ṣe rere nílé ayé o, ire mà lójùkà*
*Kàkà kólóore kú sípò ìkà, bó bá fẹ́ jìn sọ́fìn á bọ́*
*Ayé ẹ dákun ẹ gbà gbà gbà gbà gbà*
*Ẹ gbàyí ẹ gbéyìí wo*
**Ègbè***: Ẹ dákun ẹ gbà gbà gbà gbà gbà*
*Ẹ gbàyìí ẹ fi kọ́gbọ́n*

Saheed Ọ̀ṣùpá jẹ́ kó yé àwọn olùgbọ́ rẹ̀ pé **ire ló pé, ìkà ò pé.** Ó sọ̀rọ̀ nípa ẹ̀san gẹ́gẹ́ bí òwe àwọn àgbà tó sọ pé níjọ́ tí a bá ti ń ṣebi bí abẹ́rẹ́, ọjọ́ tó bá tó ọkọ́ rọ ní pani. Èyí ni pé gbogbo ìkà yòówù kí ẹ̀dá ṣe tí ó rò pé òun ti mórí bọ́, ẹsan ń dúró de onítọ̀hún ṣe iyán ogún ọdún a kúkú máa jó ni lọ́wọ́ fẹlifẹli.

Nínú orin yìí kan náà ó tún mẹ́nu ba ìwà ọ̀lẹ.

*Lílé: Ká rísẹ́ nlẹ̀ ká tún má ṣiṣẹ́, baba ọ̀lẹ́dàrùn*
*Ìṣẹ́ mà ló ń pàyàn ṣiṣẹ́ má ṣọ̀lẹ mà niṣẹ́*
*Kéèyàn ma ṣiṣẹ́ fónísẹ́ ìyẹn làṣe dànù*
*Ká ṣiṣẹ́ ká tún má jèrè tabá rérè jẹ mà niṣẹ́.*

*Torí bóníṣẹ́ ń ṣiṣẹ́ o, bóníṣẹ́ ń ṣiṣẹ́ tọ́lẹ ń ṣọ̀lẹ*
*Ègbè: Tó sọ pémikọ́ n kì í ṣonísẹ́,*
*Tó láyé yìí tí mo wá n ò wá ṣiṣẹ́*
*Bó bá paṣẹ́ jẹ, éèle pàṣẹ̀ jẹ*
*Torí tó bá dìgbà tóníṣẹ́ bá ń jèrè iṣẹ́*
*Ìgbà yẹn lọ̀lẹ á tó mọ̀ póun gan ti jèrè ìmẹ́lẹ́.*

Kedere ni àlàyé orin yìí hàn síta, ọ̀lẹ kò dára, dandan ni fún ẹni tó bá fẹ́ lọ́rọ̀ láti ṣiṣẹ́ ká sì fi àdúrà tì í lẹ́yìn ká má ba à ṣiṣẹ́ fún ẹlòmíràn jẹ. Ó sì fi ọ̀rọ̀ àwọn àgbà kádìí rẹ̀ pé **iṣẹ́ lògùn ìṣẹ́.**

**Ìyánrọ̀fẹ́rẹ́ láti inú Kùránì**: Gẹ́gẹ́ bí a ṣe ti sọ síwájú pé ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí ni Saheed Ọ̀ṣùpá, èyí fi ara hàn nínú àwọn orin rẹ̀. Nínú àṣàyàn orin fún kókó yìí ("Barrybration"), orin yìí ni Saheed Ọ̀ṣùpá kọ láti fi sọrí àgbà ọ̀jẹ̀ olórin fújì; Barrister tí ó kú ní ọjọ kẹrìndínlógún oṣù kejìlá ọdún 2010, bí a bá wò ó láti inú orúkọ Barrister ni Saheed Ọ̀ṣùpá ti ṣẹ̀dá àkọlé orin náà ("Barrybration").

Ó lo ẹsẹ Kùránì láti ṣíde orin náà, ó lo anfani yìí láti ṣe àlàyé nípa ikú (Àsàráílù gẹ́gẹ́ bí àwọn Mùsùlùmí ṣe máa ń pè é). Ó ṣàlàyé àjọṣepọ̀ tó wà láàárín ènìyàn, ikú àti ilẹ̀. Ó lo ẹsẹ Kùránì (Al-Baqarah 30) *'qala rabbuka lilmalaikati innee jaAA-ilun fee alardi khaleefatan'*

Ẹ̀kọ́ to mú jáde fún àwọn olùgbọ́ rẹ̀ ni pé ọjà ni gbogbo ẹ̀dá wá ná láyé, ká ná ọjà náà tán ká sì padà. Kò ṣàìmẹ́nubà á pé ohun tí a bá ṣe sílẹ̀ ni yóò kù fún ènìyàn lẹ́yìn ikú yálà rere tàbí ibi, ó tún fi kún un pé gbogbo oge àṣejù, Ìbàdí àrán, olójú arédè gbogbo rẹ̀ pátápátá ní ilẹ̀ ó fi ṣe oúnjẹ jẹ. Èyí túmọ̀ sí pé kí gbogbo ẹ̀dá máa rántí ọjọ́ ikú láti máa ṣọ́ ìwà hù.

## Ǹjẹ́ àwọn ète náà jẹ mọ́ ọ̀nà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá?

Ní ilẹ̀ Yorùbá onírúurú ọ̀nà ni wọ́n máa ń gba láti dá àwọn ọmọ wọn lẹ́kọ̀ọ́, gẹ́gẹ́ bí a ti se mọ̀ pé ẹ̀kọ́ láyé àwọn babańlá wa kìí ṣe nínú yàrá ìkẹ́kọ̀ọ́ tàbí kíkọ sílẹ̀, èyí mú kó jẹ́ pé gbogbo ibi, gbogbo ìgbà, gbogbo ọ̀nà ni wọ́n máa ń lò láti kọ́ àwọn ènìyàn wọn lẹ́kọ̀ọ́, èyí wà lára ìdí tí àwọn àgbà ṣe máa ń pòwe pé '*ojú mẹ́rin ló ń bímọ, igba ojú ló ń wò ó*' torí pé àwọn Yorùbá kì í gbé ìgbéayé kónkója-bele, ọmọ tí wọ́n á sì bí ọmọ gbogbo ayé ni. Oríṣìíríṣìí ọ̀nà ni ènìyàn ń gba kọ́ ẹ̀kọ́ láti ìgbà kékeré títí yóò fi dàgbà, kódà lẹ́yìn tí ó dàgbà tán, ẹ̀kọ́ kò dúró, yóò máa tẹ̀síwájú titi di ọjọ́ ikú ni, èyí ni àwọn àgbà ṣe máa ń pòwe pé '*ìmọ̀ ò pin síbìkan, bójúmọ́ ṣe ń mọ́ lọgbọ́n ń peléke sí i'.*

## Ìkádìí

Lẹ́yìn ìjíròrò àti ọ̀rínkínnìwín àgbéyẹ̀wò lórí gbogbo àwọn ète ìdánilẹ́kọ̀ọ́ tí a ló nínú iṣẹ́ àkànṣe yìí ó fojú hàn gbangba pé gbogbo rẹ̀ ni ó jẹ mọ́ ọ̀nà ìdánilẹ́kọ̀ọ́ ìbílẹ̀ Yorùbá gẹ́gẹ́ bí a ti ṣe àgbéyẹ̀wò rẹ̀ tẹ́lẹ̀ ní abala tíọ́rì àmúlò fún iṣẹ́ yìí; sosíọ́lọ́jì lítíréṣọ̀, èyí tí ó fi àsopọ̀ àti ìwọ̀núbọ̀nú tí kò lódiwọ̀n láàárin iṣẹ́ ọ̀nà lítíréṣọ̀ èyí tí orin jẹ́ ọ̀kan lára rẹ̀ àti àwùjọ tí a gbé e kalẹ̀ fún, tí ọ̀kan lára àwọn kókó àrídìmú rẹ̀ fi hàn pé à ń ṣe iṣẹ́ ọ̀nà lítíréṣọ̀ láti fi àṣà àwùjọ hàn kí àwọn ìràn tó ń bọ̀ lẹ́yìn wá lè rí ẹ̀kọ́ kọ́ níbẹ̀ kí ìwà rere tó jẹ́ ìtẹ́wọ́gbà láwùjọ náà lè máa tẹ̀síwájú.

A ní ìgbàgbọ́ pé iṣẹ́ ìwádìí yìí ti mú àfojúsùn rẹ̀ ṣẹ. A ti mẹ́nu ba àwọn ohun tó yẹ láti mẹ́nu bà láì kọjá ààlà wa. Ṣùgbọ́n nítorí pé ìmọ̀ ò pin síbìkàn bẹ́ẹ̀ ni ọgbọ́n ò pin síbì kan, àwọn ohun mìíràn wà tí a tún le fi ṣe iṣẹ́ ìwádìí ní ọjọ́ iwájú. Bí àpẹẹrẹ àwọn olùwádìí ní ọjọ́ iwájú le ṣe iṣẹ́ lórí ète ìdánilẹ́kọ̀ọ́ nínú àwọn olórin mìíràn yálà fújì, àpàlà, jùjú àti bẹ́ẹ̀ bẹ́ẹ̀ lọ tí wọn forín dániílẹ́kọ̀ọ́.

## ÌWÉ ÌTỌ́KASÍ


Adébọwálé, O. (2003). *Ọ́gbọ́n Òǹkọ̀wé Alátinúdá. Lagos: The Capstone Publication.*

*Adédèjì, A.* (*2010*). *Yoruba culture and its influence on the development of modern popular music in Nigeria. PhD thesis, Department of Music, University of Sheffield*

*Adéoyè, C.L,* (*1979*) *Àṣà àti Ìṣe Yorùbá. Oxford University Press* (*PLC*).

*Adélékè, D.A.* (*2001*). *Ìfáàrà sí Orin Àpilẹ̀kọ Yorùbá, Distance Learning Center University of Ìbàdàn*

*Adéyínká, A.A and Ajíbọ́lá, A.J.* (*2015*). *Availability, use of and relevance of Yoruba songs and rhymes in pre-school education in Ondo west local government area of Ondo state. Revenue Scientifique, Geste et Vo 9. 22.332-346Augustine C.* (*1839*) *Positive Philosophy: Bathoche Books: http://dhaspriory.org>comte*

*Bámgbóṣé, G.* (*2016*). *The Artiste as a Propagandist: A Critical Analysis of Saheed Osupa's Music. The African Symposium: An Online Journal of the African Educational Research Network. Vol. 15. No. 3, pp 76-86*

*Egbokhare, O.I. and Fádípẹ̀, A.* (*2016*). *The Framing of Political Messages in Ayinla Omowura's Song-Texts. Journal of Communication and Language Arts, Vol. 7.1:43-63*

*Fádípẹ̀, I.A.* (*2016*). *Political Communication and Indigenous Popular Music: The Study of Apala and Fuji Music Genres. Journal of Communication and Media Research, Vol. 8.1.1:185 – 198*

*Idamoyibo, A.A.* (*2016*). *Indigenous Music in a New Role. Nordic Journal of African Studies Vol. 25*(*3&4*)*: 329–348*

*Ọdúnjọ, J.F. 1961 Àkójọpọ Ewì Aládùn. Longman*

*Ògúndèjì, P.A (1991). Introduction to Yoruba Oral Literature: Ibadan Centre for External Studies, University of Ibadan*

*Ògúnṣínà, B. (2006). Sociology Of The Yoruba Novel, An Introduction. Ilorin: Integrity Publication.*

*Olúdáre, O. (2018). Preserving history through popular music: A study of Ebenezer Obey's Juju music. Retrieved 23 February, 2019 from https:* www.researchgate.net/publication/32846

Olúsọjí, S. (2008). Comparative analysis of the Islam influenced apala, waka and sakara popular music of the Yoruba. Unpublished doctoral thesis.

Ọlátúnjí, O.O (1984). *Features of Yoruba Oral Poetry. Ìbàdàn: Ibadan University Press Plc.*

Yussuf, N.B. and Olúbòmẹ́hìn, O.O. (2018). Traditional Music and the Expression of Yoruba Socio-cultural Values: A Historical Analysis, Muziki: Journal of Music Research in Africa 15:2, 61-74, DOI: 10.1080/18125980.2018.1554980

## Orin Ìtọ́kasí

- Saheed Oṣùpá (1999) "Fuji Boogie," produced by Olasco Records Limited, Lagos.
- Saheed Oṣùpá (2001) "London Delight," produced by Afeezco Films International Limited, Lagos.
- Saheed Oṣùpá (2005) "Reliable," produced by Afeezco Films International Limited, Lagos.
- Saheed Oṣùpá (2011) "Barrybration," Produced by Afeezco Films International Limited, Lagos
- Saheed Òṣùpá (2012) "Capability," produced by Golden Point Music, Lagos.
- Saheed Òṣùpá (2012) "Turn by Turn," produced and marketed by Libra Music, Lagos.